**Owe**

KITA-KITA KOMỌ TI ARISIKI, KI A ŞIŞẸ BI ẸRU KO DA NKAN

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

**Asoje**

ENIA B I IYA KOSI TANI JẸ Ş [illegible]

VOL. XIII No 708 LAGOS SATURDAY SEPTEMBER 30, — OCTOBER 6, 1961 KỌBỌ MEJI (2D

# ROGBODIYAN BE SILE NI MOSALASI NLA LARIN AWON RATIBI

EKO - Ede- aiyede kan ti o bẹ silẹ nisisiyi larin awọn Oictu Mọşalaşi Jimọ nla nilu Eko, ni a gbọ wipe ohun ti o fa rogbodiyan na ni ti owo Betilimọni ati awọn owo miran ti o nwọ inu apo ijọ Mọşalaşi na.

A gbọ wipe Alaiyeluwa Adeniji Adele Keji, Ọba ilu Eko ti ranşẹ pe apa kini ati apa keji lati şe atunşe ọrọ ede-aiyede na ki o to ma a ran bi igbin ti yio wa gb'odo-gb'ọlọ da ijọngbọn ọtẹ nla silẹ bi iru eyiti ilu Eko ti f'ara gbalamọ koja ni asiko afinju Ọba wa rere Eşugbayi Eleko. Ki ọrun oni san o.

Ẹjọwọ, e fi egun Otolo to o. Kabiyesi, Alaiye, ọwọ aran o.

## Eku Ewu Ajodun Ominira Wa.

[illegible]



( Wo ọrọ re loju ewe kefa )

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**
Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA.
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA ILARO, BENIN-CITY, WARRI SAPELE ABA KANO, ZARIA, JOS
LONDON OFFICE
15 THROGMORTON AVENUE, E. C. 2
Manager : F. O. Tyrrell.
Telephone : London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbanigr London
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

**Messrs J. H. DOHERTY LTD**
Latest selections from the
**Department And SUPERMARKET**
**"BANUSO STORE"**
80/68 BROAD STREET, LAGOS
( OPPOSITE THE CENTRAL BANK AND NEW B. O. A. C. OFFICES )

# IWASU IGBORO IJO ELESIN ISESE

Nnu ipace ti gbegbe awon ajo tabi Ijo Elesin Isese eniyan dudu (Ancient Religious of African Descendants Association) se ni ile Oloye Fagbemi Ajanaku, Araba, Eko ni ojo Abameta ti nse ojo ketalelogun osu yi. Nwon pinnu lati se Akanse Iwasu Igboro ni ojude Oloye Araba Eko ni, 55, Okepopo St. ni ojo osę (Sunday) ti nse ojo kini osu ti o nbo (1st of Oct) lati le fi ope fun Olodumare ti o je ki odun kan ti ilu Nigeria eba Ominira se oju emi, ati lati wure fun aseyori taki fun awon Alakoso ilu wa ki Olodumare le ma to won si ona nigbagbogbo. Iwasu na yio bere ni deede agogo mefa abo irole (6.30 p.m.)

Adupe o, Olotu, Oluwa yio ma pelu, yio si ma gbe pelu re, yio si ma gbe iṣe re ga. A se

Abiodun Basorun Akowe

# ODUN ORUNMILA

(Lati Owo Ogbeni Gbadebo Dosunmu)
Olulana, Ijo Ti (Afrika) Orunmila (W. A.).
Eriwo Ya (Meta) Ayagbo Ayato (Meta).

Nwon ni lati gbon fe-fe-fe. Ikorira ati Ilara ni lati wa fun nwon ni ona gbogbo, nitorina gbogbo enyin omo-bibi ati Ojulowo omo Oduduwa e ji ninu orun, e fara ndo, ki oro yi nwon ba. E dide fun iranlowo nwon lohun gbogbo-gbo. Lotito Orile-Ede yi kere, sugbon e su ki e se ara yin ni ośuśu owo, nitoripe Ete Awo' ni Ete Ogberi.

Orile-ede wa ko ni ite o. Ase "Bi wonikegbe jo l'aiye ki egbe jo l'Orun T'agogo ni bori, T'ope yo gbamgba T'Ifa yo".

E mu ti Ifa se e feran ara yin. Bi iwo bati fe ki a se si e ni ki o se si alakeji re. Ma se gbagbe, Ofin Ekerinla wipe :- "Ase-ni-nse ara re lose. nitori, a-ki i-fi'ka deru ki ogun.

(Wo yoku loju ewe kefa)

# Odomokunrin Kan Gun Iyawo Re Lobe.

SURULERE - Odomokunrin kan bi omo odun merin-dinlogoji ni ojo ori re, ti nwon npe oruko re ni Jimo Aremu ni a gbo wipe nwon gbe oku re jade ninu Kanga ni ale ojo monday osę yi.

Ohun ti a gbo nipe Aremu ti o ngbe No 7, Opopo Kadiri, ni Surulere pelu iyawo re ni wipe gbolohun aso kan ti won po ti o mu Jimo Aremu binu tepo ti o fi gun iyawo re lobe, lehinna ko le duro wo mo, bi o ku tabi ko ku, ki o to salo bo sinu Kanga ti on na ku si.

Efun ni eyi tabi edi? !

# APEJE AWON ILU TI O MBA GESI SEPO



OGBENI Dumcan Sandys, Akowe egbe awon ilu ti o mba Gesi sepo ni o mba Alhaji Kabiru Bayero, M. P. soro nibi apeje nla nilu London laipe yi.

A (?)u ilu ti o pej..., ese sibi apeje na e ni ogofa enia lati orisirisi ilu.

# Nwon Fi Olopa Sun

# Esun Aji Basikulu

Kano - Olopa ti Nigeria kan ti o nṣiṣe ni Ogba Keluwe Kano, ti oruko re nje Weston Numan, ni nwon nu wa siwaju adajo ni Kotu Makurdi fun esun ole aji basikulu, ti owo re je ponun meji-din-logun ti o je ti Atunkekese Malam Sanni.

Awon olopa so wipe ni ojo keji - din-logun osu June odunni, ni Numan haya basikulu lowo Atunkekese, Malam Sami, o si ta fun Onisowo kan ni pọun mewa.

Nwon ko tile kere oro lowo re, adajo fi gbigbo ejo na si ojo kokan-le-logbon osu October, nwon fi olopa na si itimole.

# ITAN AWON ORE MEJI

( Lati ọwọ F. O. Ọlasisi )

NI gbati laelae awọn ọrẹ meji kan wa ti oruko wọn amaje Bọlaji ati Olușọla ọdọmọ kunrin ni awọn mejeji nwọn nsi nlọ si ile ara wọn, nwọn nsi ma ba ara wọn jẹun .

Ni ọjọ kan wọn de ile Olușọla nwọn a jẹ ajẹti onjẹ ti nwọn ba si de ile Bolaji, da meji onje ti mama rẹ bu fun ni yio gbe sile, ore bẹ fun igba pipẹ, nigba ti ọdi ọjọ keta wọn ti jẹ ajẹti onjẹ ni ile Olușọla, nigba ti nwọn de ile Bọlaji Mama rẹ si bu ọpọlọpọ ọbẹ fun u, osi gbe wọ iyara, o da onjẹ na si meji, bi o ti nșe tẹlẹ, ọrẹ rẹ si bere pe ki nișe ti ọbẹ yi bere loni ?

Ko ree rara ni iya Bọlaji o wo ile o si ba obẹ na nibiti wọn ti de mọle si, o si gbe wa ba Bọlaji nibiti nwọn ti njẹun lọwọ, o si bere biotiri ? Bọlaji kole sọro mọ rara. Bẹni iya abuso rẹ dahun pe ke na ni ẹgbọn on ti nșe tẹle ti nwọn bafẹ jẹun ti nwọn ba si jẹun tan, yio wa eyi ti ofi pamọ na yio si jẹ

Igba ti Olușọla fẹ sare, o sọ wipe Bọlaji Olojoro oni wa Buburu enia I tan na si ko wa wipe kọ ama se oju kokoro, Papa fun awọn ọmọde kekeke ti wọn nlo si ilewe, awọn ẹlomiran yio ba ọrẹ wọn na gbogbo owo ọwọ rẹ tan ti oba di Igba tirẹ yio ko Ijongban balẹ.

---

# OGBOJU ODE P'ERIN L'APAFON"

IBADAN - Ni ọjọ ọsẹ ti o kọja ni awọn ara abule Bogunbe nitosi Omi Iddo ni Agbegbe Ibadan gbekuta ti nwọn pinnu lati f'opin si wahala ati Idamu ti ẹranko nla kan ti nwọn npe ni Erin nko ba wọn nigbakugba.

Awọn ọdẹ bi melo kan ni nwọn mura ti wọn si gbe ibọn wọn lati wa Erin na lọ, ki nwọn le fi pẹki-ko-pẹki Nigbati nwọn f'oju kan Erin na, ni ẹnikan ninu wọn sọ wipe ki nwọn jẹki on ta ọwọ si, pẹlu bọn rẹ ołoju kan ti Oyinbo, ki ișe Șakabula o, o yin bọn kan, o si ba ni ọwọ-ija mọ agbari rẹ, lọgan, o tun f'omiran si, o tun fi si to bi ibọn mẹrin tabi marun, ki o to sa kuro ni agbegbe ibẹ.

Nigbati ina ogun jo ẹranko na, o run igbo lọ bi-ilẹ-bi-ẹni, agbara-gbabọ wiwo l'o gbẹhin rẹ. Nigbati o wo sibiti o ti kọkọ yin nibọn, ni awọn ara abule ati awọn enia gbogbo-agbe Omu Iddo nrọ wa wo Erin na.

# Oyinbo Gesi Se Awari Ogun Ti Yio Da Emi Duro



Awari egbogi kan ti awọn Ọlọkọ Ofurufu ti Gesi șẹșẹ șe ni ogun kan ti o dabi eyiti a nwọ lọ ọ onișẹ ọko Ofurufu kan, Ọgagun John Billingham, ti o nmu yi.

Ogun na je eyiti yio mu a se emi nwon enia ro ninu oko Ofurufu ti o ba nilati so 'ale ni Ilẹ gẹju tabi okun yanrin Sahara.

---

# OKU'JA WOLU

NIGBA TI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA OJA KOTA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI ŞE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONI. ŞOWO LE ŞE TI ỌJA RẸ YIO FI MA TA BI IŞU AKARA GBIGBONA.

**E Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin ELETI-OFE**

# ASOJU IJOBA ILU OYINBO



Eeiti a nwo aworan re yi ni Alabojuto Ina wo Ijoba ilu Oyinbo Qlola Viscount Kilumir, ni yio wa se oju fun Ijoba Ilu Oyinbo Gesi, nibi ayeye ajedun odun kan Ominira ile wa Nigeri ti ao se ni ojo kini osu October odun ni.

Alabojuto awon ti o mbe labe Gesi, Oloye nla Earl of Perth ati Alabojuto awon ilu ti o mba Gesi sepo, Ogbeni C.J.M. Alport ti yio ba Alabojuto Ieawe Ijoba wa siba ayeye na.

Qiori julo Qmoba'obinrin Alexandra yio wa soju fun Alayelowa Oba Obinrin Elizabeth keji.

# ITAN AWON ORE MEJI

Lati owo F. O. L...s.

Ijapa ati obo je ore timo timo, ni ojo kan nwon jijo wo si oja laise ni Ijapa ni, ki Olorun ma jeki ora ti ako mo owo re ti a ko mo ese re di ti wa o. Oba ko fi esi kankan rara.

Ijapa duro, o ni obo iwo ko le se amin ni, obo si dahun wipe igbati on o ma wi okan ti ori ki o to so be, o si so fun obo pe ti o se amin, Obo ni on ko le se amin, Ajapa si ko buru.

Ni ojo kan o si lo dinakara ori o gbe ru, o di odo Ekun, o si ... okan fun Ekun o ni ohun adidun ti on mu wa fun u eiyi, nigbati o gba, o to la o si ti si e...u oni ha! kilo dun to bayi? nibo lo ti ri nkan ti o dun to bayi? ni Ijapa fesi pe Igba obo ni enje yen.

Ekun si wipe igbe obo ni o dun to bayi. Ijapa si gba ...ri iyanju pe ki o ranse lo pe obo ti o ba de ki o ki mole ki o bere si gba ninu pe ki o sv didun. yio si su d dun fun o ti o to la.

O si kuro ni odo Ekun, ni ojo keji Ekun ranse pe Obo nigbati Obo de odo re o si ki mole o bere si gba ninu pe ki o su didun. O si fi ibeeu bojo su igbe gbigbona, Ekun si to igbe na la, o ni ko dun to eyi ti Ijapa mu wa fun on, oni tun gba ninu ni kosekose.

Omi bere si kan loju obo, o si fere ku, emi kan lo ku si ninu, ti Ekun fe fi sile, lo ba nlo, o si fere ku, emi kan lolu si inu, ti Ekun lo fi sile, lo ba nlo, o si pade Ijapa ni Iyen bere pe kini se o obo ti o fi nmi ihelebayi? o si ko gbogbo ejo o ro fun Ijapa bi Ekun ti se fun on Ijapa bi Ekun ti se fun on. ni Ijapa dahun pe o ranti oro ti mo so ni jelo t iwo ko dahun amin si, obo si ke t'anu tanu pe on ranti oro na, ni Ijapa si so fun pe nje, se Iwo le se amin. nisisiyi, obo si dahun pe on yio se amin, o si bere si se Amin titi di oni yi.

# ASOJU ILU RHODESIA GBALEJO



Ogbeni A.E.P. Robinson ti ise Asoju ilu Rhodesia ati Nyasaland nilu Oyinbo, ati iywo re ni nwon gba awon agbe ti o ti ile Rhodesia ati Nyasaland wa lalejo fun abewo.

Ohun ti awon oja agbe wonyi wa se ni lati oju ri bi nwon ti nse ise agbe nilu Oyinbo ki nwon si ko eko nipa re, Nwon yio de ile ise Gimson (Steds) Lt. ti nwon ese irugbin, ati ile ise Pfizer, ibiti nwon nse ogun ohun ogbin oko nilu Sandwich Kent pelu

# Asoju Awọn Ilu Ti o Mba Gesi Sepo Iibi Apeje Nilu London



Alhaji Ẹni-ọla Isa Kaita, C. B. E. Atapọjuto d.o .. ipinle Ariwa Nigeria, Sir James Robertson, Gomina Gbogbo-gbo akoko nilu

Nigeria ati Sir George Oehlers, O. B. E. Alẹṣe Ile Igbimọ ilu Singapore ni awọn pade ... ilu apeje awọn Aṣoju ilu ti o mba Gesi ṣẹpọ nilu Oyinbo.

Eyi ni ipade keje ti g... ilu ti o mba G.s ṣep... o s... le ni ẹgbẹfa enia ti o wa lati orí-ṣiriṣi ilu, ti awọn ti nṣe a... ... ...rl Ilu Oyinbo ki Alaiyaluwa Ọba obinrin to ṣi ipade na ni ọjọ kẹd...gbọn oṣu September yi.

## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ti o kun Fun Irohin Aladun

# AKIN ADEMOKOYA TI ILU OYINBO DE.

EKO - Ọgbẹni Akin Ademokoya ti o lọ kọ iṣẹ Alakoso (Management) ninu ile ẹkọ iṣẹ-ọwọ ti awọn npe ni Ealing Technical College ati Woolwich Polytecnic, nilu nla London pada de laipẹ yi pẹlu ẹkunrẹrẹ iwe ẹri wipe o yege ninu ẹkọ rẹ.

Ọgbẹni Akin Ademokoya yi ni ọmọ bibi inu Oloye S.A. Ademokoya Ọba-Odo ti Ilesha ti o si tun jẹ adajọ kotu ibilẹ ilu Ilesha.

Awọn Oniṣowo U.A.C. ti gba Ọgbẹni Akin Ademokoya nilu Oyinbo nwọn si jẹ Alajumọ-ṣepọ pelu ile kiṣe Scottish Midland France Company, ti eka ile iṣe wọn fere yika gbogbo ilu Oyinbo.

A fi iwe wa ki Oloye S. A. Ademokoya ku orire a si ki Akin ku abọ ekọ re ti o kọ ni akọ yọri.

# Ile Adura Daru! Olori Ndu Ori R..

KABBA - Ile adura awọn Serafu ati Kerubu ni ilu Kabba daru ni aipẹ yi nigbati ọkunrin kan ti eri rẹ yi yọ ad.. dani ti o si bẹ wọle si n awọn Aladura, ẹru j.jẹ de ba gbogbo awọn enia ti o wa ninu ile is.n na.

Gbogbo awọn enia ti o wa j'ọsin l'o nsa asala fun ẹmi wọn, nigbati ọkunrin na nfi ọwọ dọn oju ada rẹ pẹlu ibura wipe ẹniti o ba gboju-gbaiya (sunmọ en, yio f'oju kan Olodumare.

Ki a ma fa ẹrọ gun mọ, awọn ọlọpa ibilẹ ni nwọn wa ba wọn mu, nigbati gbogbo ero ile isin ti tuka ti Ṣ.ṣi mọ yanga. Ọkunrin na mbẹ ni itimọle n'sisiyi.

## Eleti-Ofe D'araba

# PAYAL

Ati orişirişi Awọn Egbogi Ipara Miran jẹ Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi fun "Ipara" ti awọn ailera tabi aridi wọnyi ba nyọ lẹnu ni ode ara. Ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun ni gbakugba.

Aleẹọ, Egbo ẹsẹ orişirişi tabi ti o jọ rẹ ti pẹ bi adajinọ Egbo, Ekusa tabi Lapalapa, Ela, Ara sinu, Akọ Iparun Sobiya ati orişirişi arun "ARA" miran gbogbo.



Gbiyanju lati dan ọkan ninu awọn egbogi kokoro titun ti awọn ara Ilu Tatanbuln şe wo larin ijọ mẹta iwọ na yio ma robin rẹ fun awọn elomiran pẹlu Egbogi ipara wọnyi ki şe awọn rọbirọbi ti wọn nta kakiri ilu ni owo pọku. Ojulowo egbogi arun ara hanunhanun ti ko si şişi iye meji ninu rẹ ni wọn je, wọn si yatọ patapata si awọn egberemiti adimọwọ ti wọn nta kakiri Igboro ati ni igbereko gbogbo pẹlu. Kekere ati Nla.

Bere Egbogi Ajebidan wọnyi ni Şọbu awọn:-

WATERLOO MEDICINE STORES.
8, Palmchurch Sreet, Lagos,
PHONE: 22878 Nigeria. (Ọja Ita Faji)

ATI NI AWON ŞOBU IBADAN:-

IŞE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN

ADEBỌGUN PATENT MEDICINE STORES APATA AIYERAIYE STREET, ADE-ỌYỌ IBADAN


## Odun Orunmila

(O bẹrẹ loju ewe keji)

Wayi o, kini awa tilẹ ti jẹ larin awọn Orilẹ Ede Agbaiye? ati iru ẹsin wo ni tiwa yiyi? Idahun mi ni ape, "Orilẹ ede ti Oduduw-Ku-Otu-Ojire" ni Orile ede Akọda tabi akọkọ tabi agba ninu awọn orilẹ ede ni aiye. Isin Ifa tiwa yi ni ẹsin agbaiye, ti alukuluku ilu mu lọ, awọn si yi si ọna tiwọn. Ki si şe ẹsin mẹta li o mbẹ lode aiye gẹgẹbi awọn enia ti nro bikoşe ẹsin lọ mẹwa.

(Iyoku di ọsẹ ti o mbọ)

## Awọn Alabojuto Ise Ijoba Nigeria Nilu Oyinbo

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Ọgbẹni B.O. Ikeh Olugbimọ ninu Ile Igbimọ lati Apapọşe ati Alhaji Ẹnọla Isa Kaita, Alabojuto ẹkọ iwe ninu Ijọba Ariwa, Oke-Ọya ilẹ Nigeria, ti nwọn foju jẹgbadun aşọ awọn Şọja ilu Scotland ti o duro şonşọn, ti o nşọ ile işọ Edinburgh ni Olu ilu Scotland, ti nwọn lọ bẹwọ pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ miran ti nwọn wa si ipade keje ti awọn fun ti o mba Ọgọ şişọ.


# J. A. Ajao Brothers

Head Office: 10, Egerton Road,
P. M. B. 2278, Lagos Nigeria
Phone: 21521, 21522 & 21941

IMPORTS: ALL TYPES OF MANUFACTURED GOODS (INCLUDING BUILDING MATERIALS)

EXPORTS: ALL TROPICAL PRODUCTS.

SOLE AGENTS FOR:

(a) Quaker Oats Flour - (QUAKER) - CANADA

(b) PAINTS - EMULSION, Kil-Stet Wall Finish Good year Aluminium Roofcoating, etc.

(c) VETERINARY & AGRICULTURAL PRODUCTS (GERHARDT PENICK LTD.) - ENGLAND Medicine for killing rats and mice Crawling insects, Benbows Dog mixture etc.

(d) HAIRCOSMETICS & HAIRDRYERS (NEW MODEL) PEDESTAL & WALL BRACKETS AVAILABLE - (WELLA. DARMSTADT AG.) GERMANY

(e) ALL CLASSES INSURANCE - (S.B.I.) - AUSTRALIA

We deal extensively in the following: PROVISIONS, TECHNICAL & ELECTRICAL GOODS, RADIOS & RADIOGRAMMES, FANS, MOTORCYCLES, FRIGEDAIRES, ETC

BRANCHES Throughout Nigeria, including: IBADAN, OYO, AWE, OGBOMOSHO, AKURE, ISEYIN OKE-AMU, EDE, IFO, ETC.

WE ASSURE YOU OF QUICK DELIVERY OF ALL ORDERS.



E MA POLOWO OJA YIN SINU IWE IROHIN ELETI--OFE



LIVE WELL
EAT WELL
eat
"De FACTO"



**NEW ....**

When you will be doing your next purchase of shirts, treat yourself to the best from our fabulous Range . . .

ST. MICHAEL--ARROW--VAN HEUSEN
REAL BROCK--BONSIOR--AERTEX
JAYSON--FRUIT OF THE LOOM etc....

Take your choice. Then take your time and have a look of our wide range of underwear, hosiery, and ties. All famous makes that have created new standard of luxury and comfort in menswear.

# LEVENTIS DEPARTMENT STORES

MARINA—MAINLAND
IBADAN.


Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 467 Phone No 23370